# Iyipada si rere Ẹgbẹ Co-operative Thrift and Savings Society



LAIPẸ yi ni Apapọ Ẹgbẹ "Co-operative Thrift and Savings Society" ti Ile-Itẹwe Amalgamated Press of Nigeria Limited, Lagos, ṣe ẹyẹ ifunni ni iwe-aṣẹ ni 57, Igboṣere Road l'Eko.

Ẹniti o sọrọ ni ipade aṣeyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni S. O. Shonibare, Ọga Alakoso Ile-iṣẹ Itẹwe Amalgamated Press. Aṣeyẹ ọjọ na si mu idunnu ayipada si rere wa fun gbogbo ọmọ ẹgbẹ na.

Awọn ti o wa ninu aworan oke yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ati Babasalẹ wọn ati awọn alejo miran ati awọn Olotu Ẹgbẹ Cooperative. Aworan kekere inu aworan yi ni igbati nwọn wa lẹnu "faaji pẹsẹpẹsẹ" ninu aṣeyẹ na.

## Baba Ẹgbẹ Afẹnifẹre Irra sin ọmọ meji fun ọkọ

IRRA.

NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kejila oṣu kejila ọdun ti o koja yi ni Ọgbẹni Asani Dọkita, baba Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ti ẹka ilu Irra sin ọmọ rẹ meji fun ọkọ. O sin Omidan Sikiratu Abẹjo fun Ọgbẹni Mustafa Adebayọ ti ile Yeye, o si sin Omidan Rabiatu Anikẹ fun Ọgbẹni Yunusa Abẹfẹ ti ile Aro.

Nigbati ọjọ iyawo na ti ku ọjọ mẹta ni ẹsẹ awọn alabaṣẹyẹ ti pe ṣọṣọ si ile baba iyawo, ti ilu ndun,"ti awọn onirara (alagbe) nsọ tẹnu wọn ti gbogbo wọn si nla ijo mọra bi kokoro. Awọn alabaṣẹyẹ na to ẹgbaa (2,000).

Ni ọjọ igbeyawo gan an, baba iyawo ati awọn iya iyawo ha owo fun awọn alabaṣẹyẹ, nwọn si fi orisirisi onjẹ ati ọti tẹ gbogbo wọn lọrun. Irohin ko to afojuba ni aṣeyẹ ọjọ na, o dun o larinrin.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu wọn ni awọn Ọlọla J. S. Ọlawọyin; Kansilọ E. O. Ọdẹtokun; Alhaji Bakare Adeyẹmi; Imam-Agba Bello Leke; awọn Ọgbẹni Simeon Ogunlẹye; Abudulai Ọlarenwaju ati Ṣẹgun Ọlanrewaju.

Ki Oluwa fi ibukun sinu igbeyawo na, ki O fi ire kari o.

## Adetokunbọ Ademọla yio gba ọpa-aṣẹ idajọ-ododo

EKO.

NI ibi aṣeyẹ kan l'ọla, ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejila oṣu yi ti nwọn yio ṣe ni Kotu-Nla Apapọ Ijọba Naijiria ni Ọlọla James Robertson, Gomina Agba Apapọ Ijọba Naijiria yio gbe ọpa-aṣẹ idajọ-ododo le Ọlọla Adetokunbọ Ademola lọwọ gẹgẹbi Adajọ-Agba Apapọ Ijọba Naijiria.

Awọn ti yio lọ si ibi aṣeyẹ na ni Oloye Evershed (Master of the Rolls and Keeper of Public Records in the United Kingdom) ati awọn Adajọ-Agba ati awọn agbẹjọro Eko.

## Awọn ọmọ ilu Ire Oke-Okun ṣe ipade

ASAMANKESE, GHANA.

NINU oṣu kẹsan ọdun ti o kọja lọ yi ni awọn ọmọ ilu Ire ti o wa ni Ghana ṣe ipade keji ni ilu yi, awọn ti o si wa sibi pade na kakiri gbogbo ilu Ghana gẹgẹbi aṣoju awọn ọmọ ilu Ire ti o wa nibẹ le ni adọjọ enia.

Ninu ipade na gbogbo wọn f'ohun ṣọkan pe ki awọn dupẹ l'ọwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) fun ilọsiwaju ti ẹgbẹ na ṣe si ilu wọn, nwọn si tun bere fun iranlọwọ Ijọba na fun kikọ-pari ile-ẹkọ giga ti nwọn nkọ l'ọwọ nibẹ, ile-iwosan, ero-asọrọmagbesi ati omi-ẹrọ.

Lẹhin eyi nwọn yan awọn Oloye ọdun—awọn ti nwọn yan ni awọn Ọgbẹni Joel A. Oluokun, Alaga; Bello Ijaduola, Gbakeji Alaga; E A. Pọnnle, Akọwe-agba; Israel Awoniyi, Gbakeji-akọwe; awọn igbimọ ẹgbẹ ni—J. A. Ade; Caleb. B Adetunbi, Joseph Alao; Sanusi L. Balogun; M. O. Ọloyade ati Joseph Bọlarinwa.

## Adajọ da ẹniti o ṣi ọti Bọlugi ra dipo ọti Barandi silẹ

EKO.

LAIPẸ yi ni Ọgbẹni Ayọ Richards, Adajọ Kotu Kekere kan l'Eko da ọkunrin kan Daniel Ilesanmi, ara abule Makoko silẹ pe ki o ma a lọ ni alafia lori ẹsun ti ọlọpa fi sun niwaju Adajọ na pe, nwọn ko igo ọti Bolugi marun mọ o lọwọ. Ejọ ti awọn ọlọpa ro ni pe, larin igbati awọn ntu ile wo ni ọjọ karun osu kẹsan ọdun ti o koja yi ni nwọn ba ọti bolugi na ninu ile rẹ.

Nwọn tun sọ siwaju pe nigbati awọn ri awọn igo ọti na, nwọn fi odidi di wọn dada, ati pe ọkan ti nwọn fi lebẹli kọ "Sherry" si lara rorun lati pe ni Barandi nitoipe awọ ọti inu rẹ farajọ ọti waini. Lẹnu eyi ni Adajọ paapa sọro wipe "Mo ranti nigbakan ti mo ranṣẹ lọ ra igo oti-Barandi kan, nigbati nwọn si mu u de ti mo si i wo, mo ri i pe ọti Bolugi ni". Ọdaran na ti gba pe on jẹbi tẹlẹtẹlẹ, ṣugbọn o ṣe alaye pe on ṣi i ra lọwọ ẹnikan ti o nkiri rẹ ni nitoripe o jọ ojulowo ọti loju on.

## Ẹniti o ji Siga wẹwọn oṣu mejidinlogun

ILESHA.

NI ọjọ Aje ti iṣe ọjọ karun oṣu yi ni Oloye D. O. A. Oguntoye, Adajọ-Agba Kotu Ibilẹ Ilesha ju Jimọ Oladeinde ti ngbe Igbore Street, Abẹokuta sẹwọn oṣu mejidinlogun nitoriti o jebi ẹsun pe o ji Joseph Fowowe ti ngbe Araromi Street, Ipẹtu Ijesha ni idi-nla siga kan ti owo rẹ jẹ pọnun meje-abọ ni ọjọ kokanlelogun osu kokanla odun ti o koja yi.

## CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

ITUMỌ ALA KIKUN

IWE Itumo Ala 5s. 6d. Postage 7d.—J. Shoyinka care Post Office Ebute Mẹtta.

AFI-EYI ṢE NYIN NI Iranti PE ọlọ-ẹrọ Alọta ti ẹ ti mbere fun lati ọpọlọpọ ọjọ o ti de si ṣọbu AKỌSHILE BROTHERS 5, Balogun Street, West, P. O. Box 599, Phone 24395, Lagos pẹlu orisirisi Ọlọ-ẹrọ Alọgi ti o dara julọ fun size 1A, 2A ati 3A Mills. O wa fun tita fun alarapọ ti yio tun ta ati alaralọ. A nṣi ilẹkun ni agogo meje aro di agogo mẹjọ alẹ ni ojojumọ. Ki o tete wa ra tirẹ loni ki o to tan o. ALHADJI AKỌSHILE MANAGER.

Ibikibi ti o ba nlọ ni ki o ṣa ma a mu egbogi

DeWitt's ANTACID TABLETS

ajẹbidan dani




Eeri epo yio kuro were-were pẹlu hiho VIM




Eeri ti o ba taku npare bi idan pẹlu hiho Vim. Iba diẹ ni o ni lati lo, pẹlu. Diẹ lori aṣọ tutu, awo koto yio tun ma a dan. O rorun pupo! Hiho Vim nle eeri kuro. Awọn ikoko ati panu, awo-ibole-ile ati awọn iṣẹ ọda a si ma dan bi jigi.

Didan na tete nwa pẹlu hiho VIM

# Idahun Evangelist Akande si ọrọ Bọlaji Akewukewe

## Lati ọwọ Evangelist J. J. Akande, Ogbomọshọ

(O Bẹrẹ Lati Ọsẹ To Kọja)

BAKANNA ni Bibeli tun kọ wa lẹkọ rere ninu Timoteu Kejo ori 2, ẹsẹ 24, bayi pe "Iranṣẹ Oluwa ko si gbọdọ ja, bikoṣe ki ojẹ ẹni pẹlẹ si enia gbogbo, ẹniti o le koni, onisuru". Ẹ tun gbọ bi Jesu Kristi aṣaju wa ti ri, ati iru iwa Rẹ ti o sọ ninu Matteu 11: 28-30, bayi pe, "Ẹ wa sọdọ MI, gbogbo ẹnyin ti nṣiṣe, ti a si di ẹru wuwo le lori, Emi o si fi isimi fun nyin. Ẹ gba ajaga Mi si orun nyin, ki ẹ si ma a kọ ẹkọ lọdọ Mi, nitori oninu tutu ati onirẹlẹ ọkan li emi, ẹnyin o si ri isimi fun ọkan nyin... Nitori ajaga Mi rọrun, ẹru mi si fuyẹ". Nitori ẹkọ yi ni awa Onigbagbọ (Kristians) fi ma a njẹ ẹni pẹlẹ, ti a ki si fa ijọngbọn, a ki fi Bibeli tiwa pa enia, awa ki sọ enia di were. Ṣugbọn ẹkọ Mọmọdu ti sọ ẹnyin Imale di jagidijagan enia ati onija, bi Igbagbọ ati Imale ba pade lati sọ ọrọ Ọlọrun, awọn Imale ni akọkọ lati da ariwo ati ija sile, nitoripe ẹkọ buburu ni Mọmọdu fi kọ nyin.



*Evangelist J. J. Akande*

* * *

3. Mọmọdu ti ẹ npe ni Anobi nyin, o jẹ arufin gidigidi nipa ọrọ obirin. Alkurani ṣe ni ofin pe okunrin kan ko gbọdọ ni ju aya merin lo—Surat 4, ayat 3, ṣugbọn Mọmọdu ni aya mẹsan pẹlu awọn ale. Fun idaniloju, oruko awọn iyawo Mọmọdu mẹsẹsan na niwọnyi:—1 **Kadija, 2 Sauda, 3Ayisatu, 4 Hafsa, 5 Om-Salma, 6 Seinabu, 7 Safiya, 8 Mariama 9 Meimuna.** Ohun ti o tun buruju nipa ọrọ Mọmọdu nipe, ninu awọn iyawo rẹ wọnyi ọkan ninu wọn ti a npe ni **Seinabu** jẹ iyawo **Said** ọmọ-ọdọ rẹ ti o gba. Seinabu aya ọmọ ọdọ rẹ wọ o loju tobẹ ti o si gba a lọwọ rẹ fi ṣe aya ara rẹ. Nigbati awọn enia bẹrẹ si kun, ti nwọn si sọ isọkusọ si Mọmọdu nitori Seinabu ti o ja gba lọwọ ọmọ-ọdọ rẹ fi ṣe aya yi, nitori ki nwọn ma ba tun sọ isọkusọ si i mọ, nigbana ni o mu gbolohun ọrọ kan jade, o si wipe Ọlọrun lo sọ ọrọ na, ọrọ na ni Surat 33, aya 37, ti apakan rẹ sọ bayi pe, "Nigbati Said si ti pari ifẹ rẹ pẹlu Seinabu, Awa (Ọlọrun) gbe e fun ọ gẹgẹ bi iyawo, ki o ma ba si iṣoro fun awọn ti o gbagbọ lati gbe awọn aya agbasọmọ wọn ni iyawo, nigbati nwọn ba ti pari ifẹ wọn pẹlu wọn, aṣẹ ti Ọlọrun ni a gbọdọ ṣe."

Ninu ọrọ yi, Mọmọdu sọ pe Ọlọrun lo gba Seinabu fun on fi ṣe aya, Ha! irọ nla ni eyi, a ri i ninu ọroyi ti Mọmọdu tun wipe nigbati Said ko ni ilo aya rẹ mọ, ni on fi gba a fi ṣe aya. Njẹ iru iwa yi dara? Iwọ Bọlaji da mi lohun, njẹ bi ọmọkewu rẹ ba ni aya, iwọ le gba aya rẹ? Ninu Surat 33, aya 38, ọrọ na sọ bayi pe, "Ebi ko si fun woli (Mọmọdu) na ninu ohun ti o ṣe, ti Ọlọrun ti funun lasẹ' Mọmọdu purọ fi ọrọ y' da ara rẹ lare nipa aya ọmọ ọdọ rẹ t'o gba. Njẹ mo bere, Ọlọrun ha le pa a laṣẹ pe ki ọga bi Mọmọdu lọ gba iyawo ọmọ-ọdọ rẹ fi ṣe aya? Iwa Mọmọdu ni ẹ ri yi, njẹ ẹniti o ba jẹ Anobi Ọlọrun gbọdọ hu iru iwa bẹ ẹ?

Ṣugbọn Jesu Kristi Olugbala wa ko huwa agbere rara, ko ni ale, ko si ni iya-

**Wo oju ewe kejọ**


# PHENSIC

*A ma a wo irora san*




Wa a gbadun, ni kiakia, bi o ba mu Phensic. Egbogi ti o darajulọ fun iwosan ti a ni ni. Fun iba, otutu, ẹsanri ati irora ayọkẹlẹ—mu Phensic. Ri i daju pe o ni Phensic lọwọ ninu ile nigbagbogbo.




PHENSIC

Lagbaraju—yara ṣiṣẹ ju
O si dara ju Aspirin nikan lọ.



# OVALTINE

Nfun awọn ọmọde ni idunnu ati alafia




O dara fun gbogbo enia. Ovaltine jẹ ohun ti opolopọ awọn orile-ede ngmu kakiri. Gbogbo agbaiye ni okiki imarale re ti kan yika.



NIHIN NI ILERA WA ATATA WA—






*L'arọ* Andrews



Mu ara awọn ọmọ rẹ ya gaga ki nwọn si ni ilera—kọpu Andrews Liver Salt si arọwọto! Andrews ti o nta wọnin-wọnin "inu rirun ọmọde", allejẹun ati orisirisi arun inu ti o ba kọlu awọn ọmọ lairotẹlẹ.
Ṣa ti bu ẹkun ṣibi kekere kan Andrews ki o mi i pọ dada ki o si jẹki ọmọ na gbe e mu bi o ba ti nho ṣuṣu. Awọn ọmọde fẹran "tita-wọninwọnin" ati adun Andrews. Andrews a ma a mu ẹnu ya akọtun, o si ngmu inu walẹ o si nki gbogbo ohun ti o le mu irora wa wọ. Ekeji, Andrews ngmu ẹdọ-ki lagbara, lakotan, a ma a ko idọti inu ara jade pẹlẹpẹlẹ titi yio fi ko gbogbo rẹ tan. Mimu ifẹ Andrews kan a jẹki inu rẹ mọ ki o si ni alafia dada lọjọ na.

**O DUN-LẸNU**

**O nta Wọnin-Wọnin . . . O Ntẹjẹṣẹ!**

Agolo Tọlọmọde—3s. 6d. Agolo Imudani—2s. 3d.
Agolo ka lo o wo—1s 6d.

# Irin ajo mi si awọn Ilu Gẹẹsi Kanada ati Amẹrika

*Lati oju ewe kẹrin*

de ni agogo mẹta abọ gan an, ni o ba gbe wa lọ si ibudo ọkọ ofurufu ti Ilu Washington (Washington National Airport) nibiti a gbe wọ ọkọ ofurufu ti Amẹrika Airlines lọ si Ilu Albany ni agogo mẹrin koja ogun iṣẹju.

A de Ilu Albany ni agogo meje ku iṣẹju mẹdogun. Ogbeni John Hall Blackburn ti o wa pade wa si mu wa lọ si Ile Agbawọ ti nwọn ti pese sile fun wa ti a npe ni Raleigh Hotel ni 134 State Street, Albany. A de Ile Agbawọ Raleigh yi ni ẹhin agogo meje alẹ. Lẹhin ti a ti so eru wa lọjọ si yara olukuluku wa tan, ko si ibiti gbogbo wa le lọ ni ọjọ yi mọ; ṣugbọn olukuluku ni anfani a ti ṣe igbadun lọ.

Emi na si ṣe ere lọ, mo si ri i wipe bakanna ni omo nṣe ori lẹhin iya rẹ ni gbogbo awọn ilu enia funfun. Olukuluku ni o nṣe ki iyo dun ti on. Ti nwọn si nsare pe ki Ijọba kan ma le dara to ti Agbegbe (State) awọn.

Ni ọjọ keji ti iṣe ọjọ kejilelogun ni Ogbeni J. H. Blackburn mu wa lọ si Ile Ipade Ipinlẹ (New York State) ti nwọn npe ni State Capitol. A de Iyara Igbimọ Senate ati ti Assembly ati Ofisi Gomina (Governor's Office). Nwọn si so gbogbo bi Ijọba Ipinle yi ti wa si Ajọ (Congress) ti Ilẹ Amẹrika ati agbara ti Gomina Ipinlẹ yi ni lori Igbimọ Aṣofin "Assembly" ati ti "Senate".

Lẹhin eyi ni a rin wo gbogbo inu Ile Igbimọ yi kiri ki a to pada si Ile Agbawọ wa ni ọsan. Ni agogo marun ọjọ yi na ni Ogbeni Balckburn pe wa si apeje tii (tea) mimu ninu ilẹ rẹ ati lẹhin eyi ni a tun pe wa si Ile Dokita Berberians ni agogo meje fun nkan mimu (cocktails Party) pẹlu opolọpọ awọn enia pataki pataki ti o wa mọ wa. Ogbeni Berberians yi je Dokita Elekọ pataki ninu Ile Ẹkọ Gigajulọ ti New York (New York State University). A ba opolọpọ awọn akẹkọ pade awọn ti o ti Ilu Okere wa, ṣugbọn ko si ọmọ Naijiria ninu won. A tuka kuro ni ibi nkan ninu (cocktail Party) yi ni nkan bi agogo meje abọ lọ si Ile Igbimọ wa.

Ni ọjọ ketalelogun oṣu keje yi ti o di ọjọ kẹta ti a ti de Ilu Albany yi ni a lọ si Ofisi Komiṣanna ti Ẹkọ (Education Commissioner), eniti o sọ gbogbo eto Ijọba Ipinle New York fun wa nipa ti Ẹkọ (Education Policy of the State of New York). A wo gbogbo Ile-iṣẹ Ẹkọ yi ati Iṣura (Museum) ohun abalaiye ti Ipinle York Titun (N.Y.) yi ki a to dagbere fun awọn ti o nfi wa mona (Guide) pe, o digbose ni ọsan ọjọ yi; ti a si ko eru wa lọ si Ibudo ọkọ ilẹ ti Albany (albary Rly. Station). Ni agogo mefa irọlẹ koja iṣẹju mejilo ni ọkọ yi si fi ori si New York ni ibiti a gbe gunlẹ si ni agogo mẹsan koja iṣẹju mẹwa alẹ ọjọ ketalelogun oṣu kanna.

Ni ọjọ kẹrinlelogun oṣu keje yi ni a lọ wo Ile Apejọpọ gbogbo orilẹ ede gbogbo agbaiye (United Nations Headquarters). A kuro ninu Ile Agbawọ wa ti a de si ni York Titun ti a npe ni Hotel New Weston ni agogo mẹsan owuro pẹlu awọn ọmọ Naijiria ti o tẹle wa lati Washington D.C. de New York, lọ si Ile-iṣẹ Agbaiye yi.

Nko tun ni ma a ṣe atunwi mọ nipa pe ile kan dara. Eniti o si mu wa rin ile yi kiri ni Igbakeji Akọwe Eto Gbogbo Agbaiye) Assitant Secretary, United Nations Organisation) Ogbeni Bunch. A koko lọ ki Akọwe (Secretary, UNO) ki a to bere si ma a rin ile nla yi kiri. A de iyara ti nwọn ti nṣe Ipade ti Security Council, Trusteeship Council, Economic and Social Council ati ti General Assembly.

Opolọpọ nkan ni a bere nipa awọn Ipade wọnyi ti nwọn si ṣe alaye fun wa ti ngo ni gba asiko lati ma a lọ si ihin. Lẹhin ti nwọn ti ṣe wa ni alejo onjẹ launch) pẹlu awọn enia pataki pataki aṣoju awọn ilẹ nla bi India, France ati bẹẹbẹẹ tan ni a lọ wo ile ti o gajulọ ni aiye ti nwọn npe ni Empire State Building. A wo ṣifila ni ile yi. A si ra opolọpọ ohun keekeke fun iranti ninu ile ti o gajulọ ni gbogbo aiye yi.

Ni irọlẹ ọjọ yi ni alagba aṣoju Ijọba Gẹẹsi ninu Eto Agbaiye yi ti a npe ni Ọlọla Andrew Cocker ṣe wa ni alejo oti ati nkan jijẹ ati mimu, (cocktail party). Lẹhin ọrọ ati ibere idaraya ni ọdọ Ọlọla Coker yi ni a pada lọ si ile agbawọ wa fun ipalẹmọ fun ọjọ keji ti a o kuro ni Ilu York ati ni ori ilẹ Amẹrika pada lọ si Londonu ti a o si ma a bọ wa Naijiria.

Ni owuro ọjọ kẹdogun oṣu keje odupn ti o koja yi ni a kuro ni Ilu York ni agogo mọkanla koja iṣẹju mẹdogun wa si Ibudo ọkọ ofurufu ti New York (New York Airport).

Ọkọ ofurufu ti a wọ fo kuro ni New York ni agogo kan ọsan ọjọ kẹdogun oṣu na, a si ba ni Ibudo ọkọ ofurufu ti Londonu (London Airport) ni owurọ ọjọ keji ni agogo meje ku iṣẹju mẹwa. Ṣugbọn ki a mọ daju wipe agogo ti Amẹrika yatọ si ti Gẹẹsi, eyi ni wipe bi ilẹ ba ṣu ti ọjọ bora ni ilu Gẹẹsi, orun yio si ṣẹṣẹ kan atari ni ilẹ Kanada ati ti Amẹrika.

Nkan wakati mẹjọ si mẹsan ni iyatọ ti o wa ni arin akoko yi. Eyi ni wipe ni Ilẹ Gẹẹsi ati Naijiria ni akoko ti a kọ si irin-ajo yi, a o ti ri imọlẹ ni nkan wa-

*Wo oju ewe kẹsan*






# Irin Ajo mi si awọn Ilu Gẹẹsi Kanada ati Amẹrika

*Lati oju ewe kefa*

kati mejo tabi mẹsan si ẹhin ki ile to mọ ni ilẹ Kanada ati Amerika. Iyatọ yi si jubelọ bi a ba ti nlọ si Iwo-Orun Kanada ati ti Amerika si.

Ni ọjọ kerindinlogbon osu na ti a de Londonu yi, a lọ si ile agbawọ wa ti a npe ni Charing Cross Hotel. Ile agbawọ yi ni a wa ti o fi di ọsan ọjọ keji. Ko si ipade kan fun wa, afi ẹniti o ba ni ohun ti yio ṣe fun ara rẹ. A si kuro ni ibudo ọkọ ofurufu Londonu ni agogo meje irọlẹ ọjọ ketadinlogbọn, a fi ori si ona Naijiria. A de Kano lehin agogo mẹjọ owurọ, a si kuro ni Kano lehin ogbọn iṣeju. A gunlẹ s'ibudo ọkọ ofurufu ni Ikẹja ni agogo mejila ku ogun iṣeju ni ọjọ kejidinlogbọn.

Eyi ni ipari irohin irin-ajo mi lati ilẹ Naijiria lọ si ilu Gẹẹsi, si ilẹ Kanada ati si ilẹ Amerika, ti a bẹrẹ ni Eko ni ọjọ kokandinlogbọn osu karun yi titi di ọjọ kejidinlogbon osu keje ọdun ti o kọja yi.

Ọpọlpọ ni ohun ti a kọ nipa iṣelu ti Ipinlẹ, ti Apapọ Ijọba, ti Igbimọ Ijọba Ibilẹ ilu nla ati ti ilu keekeeke.

A kọ nipa orisirisi eto iṣẹ Ijọba gbogbo gẹgẹ bi awọn Ẹgbẹ Oṣelu ti ma a nṣe. A si le sọ iyato ti o wa ninu Iṣelu ti Gẹẹsi, Kanada ati Amẹrika ati iru eyiti a nfẹ fun ilẹ Naijiria ti o fi ara jọ pupọ ju.

A ni anfani lati mọ nipa aṣa awọn orilẹ ede mẹtẹta yi ati orisirisi iyato ti o wa ninu ẹkọ, idagbasoke awọn gbogbo orilẹ-ede wọnyi niwọn iba ti o yẹ fun wa lati mọ gẹgẹbi Oṣelu (Legislators). Ki iṣe wipe a lọ si awọn ilu ati ilẹ Gẹẹsi ati Kanada ati Amẹrika yi gẹgẹ bi awọn Oluwadi (Researchists), ṣugbọn gẹgẹbi oṣelu lati fi oju wa ri, ati fi eti wa gbọ ati lati wadi ki a si ṣe ayẹwo Iṣelu Naijiria pẹlu ti ilẹ miran ki a si le mọ bi ibiti a ba Iṣelu Naijiria de ni oni yi dara tabi ko dara.

Gbogbo ẹnyin ti ẹ ti bẹrẹ si irohin mi yi ka di oni, yio ri wipe mo nrohin gẹgẹbi a ti ṣe lọ ati gbogbo ibiti a de ati orisiris' bi gbogbo irin-ajo na ti mu wahala ati aayan lọwọ to. Ki iṣe wipe a lọ joko si ilu tabi ilẹ kan lọ gbadun ara wa ni, ṣugbọn a ni iriri eyiti o fi han wa wipe iṣẹ oṣelu ki iṣe iṣẹ rere rara. Ẹniti o ba si ti bẹrẹ si iṣẹ ilu ṣiṣe ti fi gbogbo ẹmi rẹ lelẹ ati anfani ti o ni fun igbeleke ilu ati ilẹ rẹ.

Mo nsọ eyi gẹgẹ bi mo ti ri irin-ajo mi na si ni, ki i ṣe wipe eyi ni ero ọpọlọpọ awa ti a lo. Olukulukule sọ bi o ti fẹ, o si e rohin gẹgẹbi irin-ajo na ba ti ri ni ọkan rẹ. Ṣugbọn fun emi gẹgẹ bi ẹnikan, mo ri ẹkọ ọpọlọpọ kọ, mo si fi gbogbo ọkan mi kọ iwọn iba ti mo ni anfani lati kọ.

Ni ipari irohin irin-ajo mi mo dupẹ pupọ ni ọwọ ẹnyin onkawe "Irohin Yoruba" ti ẹ si ba mi fi suru ka irohin na bi o tilẹjẹpe ko mu ẹkọ pataki kan wa, yio si wa ni ọkan ọpọlọpọ lati mọ gbogbo ilu ti mo ti de yi.

Mo dupẹ pupọ ni ọwọ Olotu "Irohin Yoruba" ati gbogbo awọn oṣiṣẹ rẹ fun aye nwọn fi gba mi ati fun wahala ti nwọn ṣe lati le so irohin mi na ni ede Yoruba ti o dara. Mo si wa dupẹ pupọ ju ni ọwọ Ọlọla Oloye S. L. Akintola, Alamojuto Iṣẹ Waya ati Ọkọ-ofurufu fun Apapọ Ijọba Naijiria ẹniti o toka iwe "Irohin Yoruba fun mi ti nwọn si ba mi ṣe eto ki irohin yi ma ku mọ emi nikan ninu. Eyi ni o fun mi ni ayọ julọ pe, o kere julọ ẹgbaa medogbon (50,000) enia ti gbọ irohin irin-ajo mi na gẹgẹmi itankalẹ iwe "Irohin Yoruba" ọsẹ-ọsẹ yi. Mo dupẹ fun anfani pataki yi.

Ni kukuru, gẹgẹbi owe Yoruba pe: "Eyiti o ku ni ẹhin ọfa (ogofa) ju oje (ogoje) lọ." Eyiti o ku ninu mi nipa irin-ajo yi tun pọ die si i bi a o ba ṣe atuwo irin-ajo mi na kini kini.

Mo dupẹ pupọ Olotu ọkọ Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o. Mo mu irohin irin-ajo mi na wa si opin bayi na o pẹlu iranlowọ Oluwa.

## Ọmọ-Ọba Laoye

**(LATI OJU EWE KẸJỌ)**

si fun awọn ti o bori ni ponun meji ṣile meji.

Ọpọlọpọ awọn enia ni o wa lati Oke-Okun (Ghana) fun ẹyẹ igbeyawo na, irohin ko to amojuba ni, o buaiya, o le gongo. Ehin iyawo ko ni mọ ẹni o.





**Nję o ni awọ-ara ti awọn yanmuyanmu fẹran?**



**Ṣa fi pa a-nwọn ki yio wa si itosi mọ!**

Awọn yanmuyanmu ko ni dimọ o ni awọ-ara mọ—bi o ba nfi "DIMP" pa a. Nwọn korira "DIMP". Bakanna ni awọn kokoro miran ti o mbu enia jẹ ti o si nta enia ti o ma a yọ ilera ati alafia rẹ lẹnu. "Dimethyl Phthalate" ati awọn egbogi ti o nle kokoro lọ ti a ti danwo ti o si daju dada ni a po mọ "DIMP". Bi o ba fi "DIMP" diẹ pa awọ-ara rẹ fẹrẹfẹrẹ nibiti o ba gbe han sode, yio daabo bo ẹ fun ọpọlọpọ wakati. "DIMP" ko ni oorun. Olomi tabi olori-amọ rẹ wa fun tita. Bere fun "DIMP" ni Ṣọbu itosi ọdọ rẹ

**DIMP** **Yio daabo bo ẹ nipa pe ki kokoro ma le bu ẹ jẹ tabi ki o ta ẹ**

D.7/59



**O NFUN NI NI ILERA** **O NFUN NI NI AGBARA**



Nję i mā wu ọ lati ni ilera sii? Aurọn ti ara wọn le ni inu won imā dun. O yẹ ki o mā mu "Phosferine Tonic Wine" lojojumo. Oti pupa pātāki yi yio fun ẹ ni okun, yio jeki o mā jeun dādā, iwo yio si ma sun wora. Mase jeki ārē amodi tābi irẹwẹsi ba ọ. Mā yọ, ki ara si le! Ra igo "Phosferine Tonic Wine" si, sobu onibārā ne *l'oni oloni*. Egbogi atati ni

**PHOSFERINE TONIC WINE**

*agbo ti o gbadun . . .*
*mejetitun nla—yio se o m ire.*

# Awọn ọmọ ologbe Fabiyi jade oku baba wọn

AGA-OLOWO LẸBA ITORI.

NI ọjọ Aiku ti işe ọjọ kerin oşu yi ni gbogbo awọn ọmọ Ologbe Alfred Kisimo Fabiyi, Aşiwaju Ijọ African Church, Ago-Olowo lẹba Itori jade oku baba wọn ti o jalaisi ni ọjọ kedogun oşu kini ọdun ti o kọja yi ninu Şoosi Ijọ na. Ọpọlọpọ awọn enia ni ẹbi, ọrẹ, ana ati ojulumọ ni o wa lati Eko, Ibadan, Abẹokuta ati Abule Agoro lẹba Tẹşan Ijoko.

ba awọn ọmọloku jade oku na. Eni-ọwọ Alufa E. J. Şosanya ni o şe iwasu, o si sọ ọpọlọpọ ọrọ iwuri nipa işe akikanju ti Ologbe na şe fun Ijọ na ni igba aiye rẹ.

Nigbati ọjọ ijade oku na ku arọ ni Iyaafin Janet Abeke Bamgbade, ọkan ninu awọn ọmọ oku na ti fi moto ko ogunlọgọ awọn alabaşeye, awọn onilu, ọti orisirişi ati onjẹ adidun lati Mushin lọ si ibi oku na, nwọn si şe aisun mọju ọjọ ijade. Irohin ko to amojuba, kutupu-hu nibi ijọ ati orin, aisun ọjọ na. Awọn ọmọ-oku na ni awọn Ọgbẹni Israel Bamidele, Semion Akanbi; Amos Ayinla; Samson Olu; Julius Olubọdun; awọn Iyaafin Felicia Olufunmilayọ; Janet Abẹkẹ Bamgbade; Juliana Akankẹ; Dorcas Abakẹ ati Marian Olusunmbọ.

Diẹ ninu awọn alabaşeye ọjọ na ni awọn Ọgbẹni J. A. Kusimọ; M. A. Adeyẹmi; J. A. Bamgbade; D. A. Odufoye (UAC Manager, Lagos); Eman. Ishọla; B. Fọlọrunşọ; P. A. Adeyẹmi; Kokumọ; Musafau; awọn Iyaafin S. A. Odufoye ati Theresa Olurebi Williams. Ẹhin oku yio dara o.

*Itan eni t'o s'owo t'o b'ode pade*

# Ogbẹni N.S. Shofoluwe

## pẹlu The United Africa Company jumọ şişe pọ fun owo-aşe-jere





LẸHIN ti Ogbeni N.S. Shofoluwe fi Ile-iwe silẹ ni Eko ni odun 1924, o ko iṣe oluko fun ọdun meji. Ṣugbọn nigba na ori anfani a ti ma a ṣowo o si darapo mọ awọn onişowo Niger Company. Loni o ti di onişowo pataki ni ilu Zaria, o si ti jumbu ninu owo ẹja panla, bulankiti, basikulu ati orişirisi awon oja miran.

O gba akọwe ṣobu meta ati ọpọlọpọ lebira. Gẹgẹbi osiṣe Niger Company ti o gbẹhin di The United Africa Company, Ọgbẹni Shofoluwe ti ṣe ise ni ọpọlọpọ ẹka Ile-iṣe na o si ti ni ọpọlọpọ oye iṣẹ ti o wulo. Ninu odun 1950, o da Ẹgbe onişowo ti ara re paapa silẹ ni Zaria. Iṣẹ ti o gbile pupo ni, o gbadun iranlọwo ti Ẹgbẹ Onisowo na ṣe fun un pupo nipa itọju ile ati ẹko awọn omo rẹ, ojojumọ ni o si nri awọn alakoso Ẹgbẹ Onişowo na fun owo ajumọsepọ. O si ni ireti lati tubo ma a ba awọn Egbẹ onisowo na ṣe papo lọ titi fun opolopo odun owo-ase-jere ti mbo si i.



*Ogogorun awọn onisowo enia-dudu ni o gbekele The United Africa Company lati maa mu oja wa fun won* [illegible]

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

Lati Ọwọ E. Alabi Thompson

"OLUWA ni imọlẹ mi ati igbala mi; tali emi yio bẹru? Oluwa li agbara ẹmi mi; aiya tani yio fo mi?—Orin Dafidi Ori 27 ẹsẹ 1.

1. Wọ Imọlẹ! larin okun aiye
   Ma sin mi lọ
   Okunkun şu mo si jinna s'ile
   Ma sin mi lo
   Nko şaferi ọla bi y'o ti ri
   To ẹsẹ mi, şisẹ kan to fun mi
2. Nigbakan ri, emi ko bẹ Ọ pe
   K'O sin mi lọ
   Gbana mo yan ọna mi; nigbayi
   Ma sin mi lo
   Gbana mo fẹ aiye on 'gberaga
   Jesu jọwọ, ma ranti igbani
3. Agbara Rẹ ti ndi mi mu y'o si
   Ma sin mi lo
   Ninu ẹrẹ ati yangi aiye
   Titi d'orọ
   Nigbana ni ngo ri awon wọnni
   Ti mo fẹ, ti wọn ti f'aiye silẹ.

ITAN ORIN NA.

Ọjọgbọn ati oloye ti o kọ orin yi ni Ọgbẹni John Henry Newman, ẹniti o ri iponju aisan fun igba diẹ ti gbogbo awọn iranşẹ rẹ ati awọn olubagbe rẹ si ro wipe iku ni yio gbẹhin idubulẹ aisan yi. Şugbọn o dahun pẹlu igboiyo lori idubulẹ aisan yi wipe "Imọlẹ Ọlọrun ti o ju imọlẹ gbogbo lọ, yio tan yi mi ka, emi yio si bori aisan yi". Laipẹ ọjọ, ara rẹ yipada si ilera rẹ atijọ. O si pinnu lati kọ orin oke yi. Lọna keji, o fi orin yi şe orin aro fun ọrẹ rẹ ti o bimọ marun şugbọn larin oşu meji si ara wọn ninu ọdun kanna awọn ọmọ mararun na si ku. Nitori idi eyi o gba a ni iyanju, lati gbadura wipe ki imọlẹ ti o ju imọlẹ lọ (eyiti işe Oluwa gbogbo aiye) lati şe Imọlẹ rẹ la iyoku aiye rẹ ja.

# Ijoba Ibile Eko jare Ọlọrunnimbẹ

LAIPẸ yi ni awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko pe Dọkita Ibiyinka Ọlọrunnimbẹ, ti o ti fi igba kan wa ni aye Meyọ Eko lẹjọ owo omi oşu mẹfa ti o jẹ ti ko san fun oşu mẹfa fun ile rẹ ti o wa ni 8, Turton Street l'Eko.

Adajọ ti o dajọ na si şe idajọ pe ki Dọkita Ọlọrunnimbe lọ san pọnun mẹrinlelọgọjọ şilẹ meji (£164. 2s.) ati pọnun marun şilẹ mẹtala (£5. 13s.) owo irinsẹ fun Ijọba Ibilẹ Eko.



"Nigbagbogbo ni awọn ọmọ mi ma a ngni idunnu ati ilera—




FERBELAN
TRADE MARK

*ni mo nfun wọn"*

FERBELAN jẹ egbogi atẹjẹşe ti a fi ọgbọn ijinlẹ popọ pẹlu onjẹ-adẹra ti o peye julọ ati ohun mimu ti o şe pataki fun ilera atata ati ilosiwaju awọn ọmọ rẹ.

*Ranti—Ferbelan fun idunnu, ilera awọn ọmọde.*

THE BRITISH DRUG HOUSES — LONDON
O wa fun tita ninu awọn Ile-egbogi pataki-pataki.

A BDH PRODUCT

